# IMURASILẸ FUN JÍJẸ́ ỌMỌ IBILẸ ỌRUN

## Heberu 12 ati 13.

## ẸKỌ 444 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Nitorina ni awa ṣe nfi igboiya wipe, Oluwa li oluranlọwọ mi, emi ki yio bẹ̀ru; kili enia le ṣe si mi" (Heberu 13:6).**

### Ofin ni Oke Sinai

Lẹẹkan si i ninu ẹkọ yii a tún ni anfaani ati fi nnkan wé ara wọn eyi nì ni Majẹmu Laelae ati Titun. "Nitori ẹnyin kò wá si òke, ti a le fi ọwọ kàn, ati si iná ti njó, ati si iṣúdùdu ati òkunkun, ati iji, ati iró ipè …." (Heberu 12:18, 19). Ninu gbolohun ọ̀rọ yii Paulu n sọrọ nipa bi fifun ni ni Ofin ni Oke Sinai ti mú ẹ̀ru lọwọ tó. Ilẹ mì, okiti eefin n tú jade lori oke naa, ipè si n dún kikankikan fun igba pipẹ (ẹnikẹni kò mọ ẹni ti n fun ipè naa). Eyi to lati da jinnijinni bo ẹni ti ó láyà jù lọ. Ọlọrun ti kilọ tẹlẹ pe bi o tilẹ ṣe ẹran lasan ni o fi ara kan oke naa ni akoko yii, yoo kú ni. Ọlọrun n fẹ́ jẹ́ ki mimọ́ Oun dá wọn loju daradara, nitori bẹ́ẹ̀ O paṣẹ pe ẹnikẹni kò gbọdọ sún mọ́ itosi oke naa. Ilẹ mimọ́ ni, ẹnikẹni ti o bá rin lori rẹ̀ ni akoko yii yoo kú ni iṣẹju kan naa.

Ọlọrun jẹ́ mimọ́ bakan naa ni ọjọ́ oni, ṣugbọn ni akoko Oore-ọfẹ yii Oun ki i maa rán idajọ kánkán nigba ti ẹni kan bá ṣe aibu ọla fún iwa mimọ́ Rẹ̀. O lọra lati binu O si kún fun aanu. O na ọwọ́ Rẹ̀ jade O si n wi pé, "Ẹ wá sọdọ mi." Jesu fẹran wa to bẹẹ gẹẹ ti O tilẹ sọkun fun awọn ẹlẹṣẹ. Oun mọ̀ ju bi awa ti le mọ̀ lọ nipa bi ọrun apaadi ti banilẹru tó, Oun kò si fẹ́ ki ẹnikẹni lọ si ibẹ̀.

### Idajọ ti O Tobi Jù

Idajọ wá si ori awọn eniyan ti wọ́n ṣe aigbọran si Ọlọrun nigba ti O fun wọn ni Ofin ni Oke Sinai. Awa ni Majẹmu ti o Dara Jù bẹ́ẹ̀ lọ nisisiyii, Olugbala wa alaanu onifẹ, pẹlu ọwọ Rẹ̀ ti ó nà jade (lati gba ni), ti san igbese irapada wa. Njẹ iwọ kò ha rò pé awọn eniyan ti wọ́n bá ṣe aigbọran si Ọlọrun ni akoko yii yẹ lati lọ si ọrun apaadi? Ọlọrun ti ṣe ikilọ pe idajọ ti o tobi jù lọ yoo wá si ori awọn eniyan ti kò fi ti Jesu ṣe ni akoko yii. Nigba ni oke mì tìtì, ṣugbọn nigba ti Ọlọrun bá dide lati ṣe idajọ lẹyin ayé ti wa yii, ọrun pẹlu ayé ni yoo mì tìtì papọ. Ni tootọ Peteru Apọsteli sọ fun ni pé: "Ṣugbọn ọjọ Oluwa mbọ̀wá bi olè li oru; ninu eyi ti awọn ọrun yio kọja lọ ti awọn ti ariwo nla, ati awọn imọlẹ oju ọrun yio si ti inu oru gbigbona gidigidi di yíyọ, aiye ati awọn iṣẹ ti o wà ninu rẹ̀ yio si jóna lulu" (2 Peteru 3:10).

### Iṣoro

Paulu fún wa ni itọni kan ninu Heberu 12 ati 13 nipa bi a ṣe le murasilẹ lati pade Jesu, nipa bẹẹ ki a si bọ́ kuro ninu idajọ gbogbo. Boya a ti ni igbala a si ti n fi igba kan sin Ọlọrun pẹlu otitọ ọkàn, ṣugbọn bi akoko ti n kọja ti Jesu kò si dé, awọn ẹlomiran le di alaibikita tabi ki ó sú wọn lati maa sin Ọlọrun. Wọ́n le rò pe awọn ni iṣoro tabi idanwo pupọ, wọ́n si le wòye pe njẹ ó ṣanfaani rara (lati maa sin Ọlọrun). Ranti pe Jesu pẹlu ni iṣoro. Ọpọlọpọ eniyan kọ̀ Ọ́, wọn kò fẹran Rẹ̀; ati ni opin gbogbo rẹ̀ O ni lati kú ni ori agbelebu. Awa kò i ti i jiya ohunkohun ti o buru ti a le fi ṣakawe iyà ti Jesu jẹ fun wa. Eyi yẹ ki o fun olukuluku ni iṣiiri lati duro ṣinṣin titi Jesu yoo fi dé.

Nigba miiran a le ṣe nnkan lai jẹ pe a pilẹ fẹ ṣe e, tabi ki a ronu jinlẹ ki a to ṣe ohun ti a kò gbọdọ ṣe, awọn obi wa tabi awọn alufaa wa le bá wa wí. A kò gbọdọ bá wọn jà nitori ibawi naa tabi ki á dá ara wa lare. Ẹ jẹ ki a mura lati huwa daradara lori awọn itọni ti a gbà. Bi awọn obi bá fẹran awọn ọmọ wọn ni tootọ, wọn yoo bá wọn wí bi wọ́n bá ṣẹ̀. Wọ́n n fẹ́ ki awọn ọmọ wọn jẹ́ ọmọ rere ti gbogbo eniyan yoo fẹran.

### Ibukun fun Ẹlomiran

Lẹyin ti awa funra wa bá ti di Onigbagbọ́, a ni lati ṣe ohunkohun ti a le ṣe lati jẹ́ iranwọ fun awọn ẹlomiran. Ọpọlọpọ igba ni awọn eniyan le gbagbe wahala ti wọn bi wọn bá n dù lati yọ ẹlomiran kuro ninu iṣoro. Ẹ jẹ ki a gbiyanju lati maa wà ni alaafia pẹlu ẹni gbogbo ki a má si ṣe jẹ́ ẹni ti n dá ijọngbọn silẹ. Nigba ti a ba sọ wa di mimọ́, ti a si jẹ mimọ́, Bibeli sọ pe gbogbo wa yoo ni ọkàn kan, a o si fi ohùn ṣọ̀kan. Iru iwa mimọ́ bẹẹ ni a gbọdọ ni ki a to le mura silẹ fun Ọrun. Ọlọrun ki yoo gba awọn eniyan ti ko le ba awọn ẹgbẹ́ wọn ṣe nnkan pọ̀ si Ọrun. Ọrun yoo jẹ́ ibi ayọ̀ nibi ti olukuluku eniyan yoo wà lalaafia.

Eṣu n fẹ ki awọn eniyan pẹyinda, nitori bẹẹ yoo maa bá Onigbagbọ́ damọran awọn nnkan wọnni ti o ṣe pe bi o ba bẹrẹ si ronu nipa wọn yoo fun un ni ikoro ọkàn. Iru ikoro bẹẹ ninu ọkàn rẹ̀ ti gbọn igbala sọnu, nigba gbogbo ni yoo si ṣe okunfa ibanujẹ fun ọpọlọpọ eniyan.

"Ki ifẹ ará ki o wà titi. Ẹ máṣe gbagbé lati mã ṣe alejò; nitoripe nipa bẽ li awọn ẹlomiran ṣe awọn angẹli li alejò laimọ̀" (Heberu 13:1, 2).

Nnkan rere ni lati ni ọrẹ, awọn eniyan ti wọn ba si fi iwa jọ ara wọn maa n layọ lati gbé pọ̀; ṣugbọn a o ri ayọ̀ tootọ bi a ba le ba awọn ti ó yatọ si wa ṣe ọrẹ (nipa ifarada). Gbidanwo lati bá ẹni ti awọn ẹlomiran ti ṣá tì ṣe ọrẹ ki o si woye bi ayọ̀ ọkàn rẹ̀ yoo ti pọ̀ tó. Pe eniyan kan wá si ile rẹ gẹgẹ bi alejò, iru ẹni ti ki yoo ni anfaani lati san ẹ̀san fun ọ. Bi iwọ ba n pè kiki awọn ti wọn le ṣe bẹẹ pada fun ọ, o kò fi ohunkohun tọrẹ rara. O fi nnkan yá wọn ni, o si ni ireti lati gba a pada. Oluwa fẹ ki awọn eniyan Rẹ̀ jẹ ẹni ti o lawọ́.

Eyi ni nnkan ti O (Oluwa) n beere lọwọ awọn Onigbagbọ́: "Ki ha ṣe lati fi onjẹ rẹ fun awọn ti ebi npa, ati ki iwọ ki o mu awọn otòṣi ti a tì sode wá si ile rẹ? nigbati iwọ ba ri arinhòho, ki iwọ ki o bò o, ki iwọ ki o má si fi ara rẹ pamọ kuro lọdọ ẹran-ara tirẹ" (Isaiah 58:7). Nigba miiran awọn eniyan ki i tilẹ ṣe itọju awọn ẹbi wọn -- ẹran-ara wọn.

Jesu wi pe: "Fifun ẹniti o bère lọwọ rẹ; ati lọdọ ẹniti o nfẹ win lọwọ rẹ, máṣe mu oju kuro" (Matteu 5:42). Paulu wi pe: "Ninu ohun gbogbo mo fi apẹrẹ fun nyin pe, nipa ṣiṣe iṣẹ bẹ̃, o yẹ ki ẹ mã ràn awọn alailera lọwọ, ki ẹ si mã ranti ọ̀rọ Jesu Oluwa, bi on tikararẹ̀ ti wipe, Ati funni o ni ibukún jù ati gbà lọ" (Iṣe Awọn Apọsteli 20:35).

Apẹẹrẹ ibukun ti o maa n tẹle fifun eniyan ni nnkan wà ninu 1 Kronika 29:9; ni akoko naa Dafidi n beere ọrẹ fun kikọ́ Tẹmpili: "Awọn eniyan si yọ̀, nitori nwọn fi tinutinu ṣe iranlọwọ nitori pẹlu ọkàn pipe ni nwọn fi tinutinu ṣe iranlọwọ fun OLUWA: pẹlupẹlu Dafidi ọba si yọ̀ gidigidi".

**Ọna Tooro**

Imọran miiran ti Paulu fi fun awọn eniyan ni pe ki wọn jọwọ ara wọn (tabi ki wọn gbọran) fun awọn ti i ṣe olori wọn. Lotitọ, o sọ ọ ni igba meji ninu ori iwe kan naa, nipa bẹẹ o ni lati jẹ pe o pe e ni nnkan pataki. Awọn obi rẹ ati awọn alufaa rẹ "nṣọ ẹṣọ nitori ọkàn nyin", bi o tilẹ ṣe pe o rò pe ofin wọnni le jù, nigba ti ayé rẹ bá wá si opin (lai ṣe aniani ki o to di igba naa gan an paapaa), iwọ yoo mọ̀ daju pe nnkan wọnni yẹ fun ọ lati mura rẹ silẹ fun Ọrun. Jesu sọ pe ọna si Ọrun jẹ́ ọna "toro", kò si àye nibẹ fun ọ̀na ti ara wa ati ẹ̀ṣẹ̀. A gbọdọ rin ọna ti Jesu nikan ṣoṣo. "Bi ẹnyin ba fẹ́ ti ẹ si gbọran, ẹnyin o jẹ ire ilẹ na" (Isaiah 1:19). Oluwa yoo ṣe itọju awọn ti o bá gbọran si I lẹnu.

Awọn iyiiriwo ati ibawi ti o wá si ipa ọna wa ninu ayé wá lati ọdọ Oluwa - bi o ti wù ki o ri Oluwa fi àye silẹ fun wọn -- wọn yoo si ṣe wa pé fun Ijọba Ọrun bi a ba kọ́ ẹkọ ninu wọn. Bi a ba kọ itọni, ti ikoro si wọ ọkàn wa nitori iyiiriwo, a o padanu ẹmi wa. Jesu yoo ṣe wá ni aṣẹgun ti yoo ni ayọ̀ kikún bi a ba n bẹbẹ lojoojumọ pe ki O ràn wá lọwọ. A ni iṣẹgun nipa Ẹjẹ Jesu. Oun ni Oluṣọ-agutan wa nla, yoo si ṣamọna awọn agutan Rẹ̀ lọ si papa oko tutu bi wọn ba n tẹle E.

## AWỌN IBEERE

1. Ki ni ṣẹlẹ ni Oke Sinai ṣaaju ki Ọlọrun to fun wọn ni ofin?
2. Iru idajọ wo ni a rán si awọn eniyan ti o ṣaigbọran si Ofin?
3. Ki ni yoo mì nigba ti Jesu ba pada wa si ayé fun idajọ?
4. Ki ni eniyan le ṣe ti o le ràn án lọwọ lati gbagbe wahala rẹ̀?
5. Ki ni isọdimimọ́ maa n ṣe fun awọn eniyan?
6. Ki ni Apọsteli naa sọ nipa ṣiṣe alejò?
7. Iru ọwọ wo ni a ni lati fi mu awọn ti wọn n ṣọ́ ẹṣọ lori ọkàn wa?
8. Bawo ni a ṣe le bori gbogbo iyiiriwo wa?